# ÀWỌN ILÉ-ÌWÉ ÌJỌBA TI AGBÈGBÈ BALTIMORE

Verletta White ♦ Interim Superintendent ♦ 6901 North Charles Street ♦ Towson, MD ♦ 21204

Ẹbí BCPS Ẹbí,

Ní Àwọn Ilé-Ìwé Ìjọba Ti Agbègbè Baltimore (BCPS), a mú ìlera àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti òṣìṣẹ́ wa lọ́kúnkúndùn gidigidi. Láì sọ fún wa kí á ṣe bẹ́ẹ̀, BCPS ti ṣe àyẹ̀wò àwọn orísun omi ilé-ìwé nítorí lẹ̣di láti ọdún 2016.

Ohun tí ó ti yí padà ni pé ìpínlẹ̀ náà ti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìlànà nípa àyẹ̀wò lẹ̣di fún omi mímu ní àwọn ilé-ìwé. Àbá Ilé 270 ni a bu ọwọ́ lù ní May 4, 2017, tí COMAR 26.16.07 sì bẹ̀rẹ̀ síí fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ ní April 9, 2018.

Gẹ́gẹ́ bí àwọn ìlànà tuntun náà ti pè fún, BCPS yóò máa ṣe àyẹ̀wò omi láti gbogbo àwọn tí ó lè jẹ́ orísun omi ní gbogbo ilé-ìwé ní ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2018-2019. Àwọn ilé-ìwé BCPS tí a ti kó ṣáájú ọdún 1990 ni ó ní omi inú ìgò fún mímu láti ọdún 2016. Àwọn ilé-ìwé tí a kọ́ ní ọdún 1990 àbí lẹ́yìn rẹ̀ ni a ó pèsè omi inú ìgò fún títí da ìgbà tí èsì bá bá ipele tuntun ti ìpínlẹ̀ tí íṣe ìpín ogún nínú biliọnu kan mu.

Kí a tó gba àwọn àpẹẹrẹ fún àyẹ̀wò, omi gbọ́dọ̀ rogún sínú àwọn ọ̀pá omi náà fún wákàtí méjọ sí méjìdínlógún. Nítorí náà, àwọn àpẹẹrẹ omi ni a ó gbà ní òwòòwúrọ̀ Ọjọ́ Àbámẹ́ta, bẹ̀rẹ̀ láti September 22, 2018.

Àwọn àpẹẹrẹ omi ni a ó ṣe àyẹ̀wò wọn ní ilé àyẹ̀wò tí ó dá dúró tí ó ní ìwé ẹ̀rí láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀ka Àyíká ti Maryland Department. Gbogbo ilé-ìwé ni yóò fi èsì náà ránṣẹ́ sí àwọn òbí, alágbàtọ́, àti òṣìṣẹ́. A ó tún jẹ́ kí èsì náà wà ní àrọ́wọ́tó ní ojú òpó BCPS àti àwọn ojú òpó ilé-ìwé, títí dórí àwọn ìgbésẹ̀ kánkán àti àwọn ìgbésẹ̀ tí ó kàn tí ó bá yẹ láti ṣe bẹ́ẹ̀.

Tí orísun omi yòówù bá ní èsì lẹ̣di tí ó ju ipele ti ìpínlẹ̀, ohun tí ó ngbé e wá ni a ó tì pa tí a ó sì pààrọ̀ rẹ̀. Ohun tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ ngbé omi wá náà kò níí wà ní àrọ́wọ́tó fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àbí òṣìṣẹ́ títí da ìgbà tí àwọn àlékún àyẹ̀wò bá fihàn pé èsì náà bá ipele ti ìpínlẹ̀ mu.

Òfin Àìléwu Omi Mímu ti ìjọba àpapọ̀ kàn nṣe àbójútó àyẹ̀wò lẹ̣di ní àwọn ilé-ìwé tí ó nlo omi tí àwọn ará ìlú nlò. Mẹ́sán nínú àwọn ilé-ìwé wa ni ó ní kànga, tí a sì ti ṣe àyẹ̀wò àwọn kànga yẹn nítorí lẹ̣di bí a ti fẹ́..

Lẹ́yìn ọdún àyẹ̀wò ìṣáájú yìí, a ó máa ṣe àyẹ̀wò àwọn orísun omi ní àwọn ilé-ìwé náà ní ọdún mẹ́ta mẹ́ta.

Ní Agbègbè Baltimore, ohun tí ó nfa májèlé lẹ̣di jùlọ lọ́dọ̀ àwọn ọmọdé ni ọ̀dà oní-lẹ̣di tí a nrí ní àwọn ilé tí a kọ́ ṣáájú ọdún 1978. Jọ̀wọ́ rántí láti pa àwọn ọmọdé mọ́ kúrò níbi ọ̀dà oní-lẹ̣di àti ekuru, kí ẹ sì fiyèsí àwọn nnkan tí ó ní lẹ̣di, títí dórí àwọn ìpápánu, àwọn ohun ìṣeré, àwọn ohun ìṣaralóge, àti yẹ̀rí etí.

Fún àwọn ìbéèrè nípa ṣíṣe àyẹ̀wò omi mímu ní àwọn ilé-ìwé wa, jọ̀wọ́ kàn sí David Glassman, alábójútó Àwọn Ìṣẹ́ Àyíká ní 443.809.6310 àbí dglassman2@bcps.org. Fún àfikún ìfitónilétí nípa fífi ojú winá lẹ̣di, jọ̀wọ́ kàn sí Ẹ̀ka Ìlera Agbègbè Baltimore ní 410.887.3725.

Fún àwọn èsì bí wọ́n ti nyọjú, kàn sí ojú ewé Àwọn Èsì Àyẹ̀wò Lẹ̣di ní www.bcps.org lábẹ́ Àwọn Kókó BCPS.

Nítòótọ́,

Verletta White<br>Alábójútó Fìdíhẹ<br>Àwọn Ilé-Ìwé Ìjọba Ti Agbègbè Baltimore

Gregory Branch, M.D., MBA, CPE, FACP<br>Olùdarí, Iṣẹ́ Ìlera àti Ọmọnìyàn<br>Ẹ̀ka Ìlera Agbègbè Baltimore